# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ÌTÀN OBINRIN MÉJÌ

## Ìtàn ...

**1 Awọn Ọba 3:16-28**

Ìdakẹ́rọ́rọ́ sọkalẹ̀ si aafin idajọ, gbogbo oju tẹjumọ́ Ọba Solomoni. O jẹ́ iyanu fún awọn iranṣẹ rẹ pé bawo ni ọdọmọde ọba yi yio ṣe yanjú ọ̀rọ̀ to wà nilẹ̀ yí.

Obinrin meji jọ n gbé ninu yàrá kan, awọn mejeeji si bi ọmọkunrin ni ìgbà kannan. Ni ààrín òru, ọkan ninu awọn obinrin naa ṣeesi sùn le ọmọ rẹ mọ́lẹ̀, ọmọ naa si kú. Nigbàtí o si ji ni owurọ, o ri wípé ọmọ oun ti kú, ninu ibanujẹ́ ọkàn, o lọ gbé ọmọ ẹnikeji rẹ ti o n sùn lọ́wọ́ si ọdọ ara rẹ, o si gbé òkú ọmọ padà sí ẹ̀gbẹ́ ẹnikeji rẹ ni ipò to ti gbe ọmọ naa. Nigbati obinrin keji dide, o ri òkú ọmọ, bayi ni idaamu nlá báa, o si n ké. Ṣùgbọ́n nigbati o wo ọmọ naa, o ri dájú kíákíá pé ki iṣe ọmọ oun. Ni kété to gbójú sókè, o ri ọmọ rẹ lọwọ obinrin keji ti wà á mọ́yà tagbara-tagbara.



Nibayí awọn obinrin mejeeji naa dúró niwaju ọba, wọn to ẹjọ́ lati fi hàn gbangba pé tawọn ni ọmọ-ààyè naa. Ọkan pariwo ninu awọn obinrin meji naa pé "èyí ni ọmọ mi!"

Ẹnikeji tun wi tirẹ̀ pé "rárá, èyí òkú ni tirẹ!"

Bawo ni ọba yio ṣe mọ ojulowo ìyá gangan bayi o? Solomoni dasi ariyàn-jiyàn wọn, o si wi fún awọn ọmọ-ogun rẹ pé, kí wọn mu idà wá, ki wọn si la èyí ààyè ọmọ naa sí méjì. Awọn ọmọ-ogun Solomoni sì ro wípé Solomoni n ṣe àwàdà ni, ṣùgbọ́n Solomoni wò wọ́n tibinu-tibinu bi wọn ti n lọra. Bi o ti mu idà rẹ to n kọ mọ̀nà lati pín ọmọ naa si mejì ni ọwọ́ rẹ. Lojiji ni ìyà ọmọ ààyè naa kunlẹ ni ẹsẹ ọba lati bẹ ọba pé "ẹ fun un ni eyi ààyè ọmọ, ki a má ṣe pa á rárá!" Ṣùgbọ́n obinrin keji wipé, "ki yio jẹ temi tabi tirẹ, ẹ là á." Bayi ni Solomoni se mọ ẹni ti ọmọ iṣe tirẹ laisiyemeji.

Ninu aṣọtẹlẹ, obinrin jẹ́ àmì fún ijọ (Jeremiah 6:2). Pẹlu ọ̀pọ̀lọpọ̀ ijọ ni ikẹhin ọjọ́, bawo ni a o ṣe mọ ijọ otitọ, ijọ ìgbà ikẹhin ti yio ni ọmọ ààyè ninu ariyàn-jiyàn? Bi i Solomoni, a gbọdọ lo ida ọ̀rọ̀ Ọlọrun (Heberu 4:12)!

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Bawo ni ìwé Ifihan ṣe fi aworan Ijọ otitọ́ hàn?
**Ifihan 12:1,2,5**
Àmì nlá kan si hàn li ọrun: __________ kan ti a fi òòrùn wọ̀ li aṣọ, oṣupa si mbẹ labẹ ẹsẹ rẹ, ade onirawọ mejila si mbẹ li ori rẹ: O si __________ , o si kigbe ni irọbi, o si wà ni irora ati bimọ, O si bi ọmọkunrin kan ti yio fi _______ irin ṣe akoso gbogbo awọn orilẹ-èdè: a si gbà ọmọ rẹ lọ sókè si ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ati si ori itẹ́ rẹ.
Àkíyèsí: Ninú aṣọtẹlẹ Bibeli, ijọ Ọlọrun dúró fún obinrin mímọ́ (Jeọ́ remiah ù:ẹ̀). Ninu Ifihan ori kejilá, a fi oorùn wọ obinrin yi li aṣọ, òṣùpá ati ìràwọ̀ - ìmọ́lẹ̀ iṣẹ́dá Ọlọrun nikan. Jesu sọ fun ijọ pe, "Ẹnyin ni imọ́lẹ̀ ayé." Matteu 5:14. Oorùn naa dúró fún ìmọ́lẹ̀ Jesu (Orin Dafidi 84:11; Malaki 4:2). Oorùn tó wà labẹ ẹsẹ̀ rẹ dúró fún òjìjí ati irú àti ẹbọ sise ti inú Majẹmu Lailai. Bi oṣupá ṣe ntàn sí ina oorùn, bẹ́ẹ̀ni ètò ẹbọ siṣe yio jẹ́ ìrànlọ́wọ́ lati fi òye ìmọ́lẹ̀ Messiah to nbọ̀ hàn (Kolosse 2:16,17; Heberu 10:1). Ìràwọ̀ mejila tó wà lori rẹ dúró fún olórí ijọ naa - ẹ̀yà mejila ti inu Majẹmu Lailai ati awọn Aposteli mejìlá ti inú Majẹmu Titun. Ẹni naa ti yio sàkóṣò orilẹ-èdè gbogbo pẹ̀lú ọ̀pá irin ni Jesu (Orin Dafidi 2:7-9; Ifihan 19:13-16).

2. Taani "dragoni pupa nlá" naa ati pé kinni o fẹ́ ṣe?
**Ifihan 12:9**
A sì lé dragoni nla naa jade, ejò lailai nì, ti a npè ni _______ , ati __________ , ti ntàn gbogbo ayé jẹ́, a si lé jù si ilẹ̀ ayé, a si le awọn angẹli rẹ jade pẹlu rẹ̀.
**Ifihan 12:4**
Ìrù rẹ si wọ́ idamẹta awọn ìràwọ̀, o si ju wọn si ilẹ̀ ayé, dragoni naa si dúró niwaju obinrin naa ti o fẹ bímọ, pe nigbati o ba bí, ki o le ______ ọmọ rẹ jẹ.
Àkíyèsí: Dragoni naa ni Satani, ẹni ti o jẹ́ wípé nígbà tí a bi Jesu, o nsiṣẹ̀ ninu awọn ijọba pagani ti Romu. Satan ru Herodu sókè, alaṣẹ kan labẹ Romu lati gbìyànjú lati pa Jesu ní ọmọ ọwọ́ nípa pípa gbọ́ gbo awọn ọmọ wẹ́wẹ́ tó wà ni Bethlehẹmu (Matteu 2:16).

3. Kilo ṣẹlẹ̀ lẹhin ìgbàtí Satani kùnà lati pa Jesu run?
**Ifihan 12:5**
O si bí ọmọkunrin kan ti yio fi ọ̀pá irin ṣe akoso gbogbo awọn orilẹ-èdè: a si _________ ọmọ rẹ lọ__________ sí ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ati si orí ìtẹ́ rẹ̀.
Àkíyèsí: Lẹ́hìn ajinde Rẹ̀, Jesu gòkè re ọ̀run ati si orí ìtẹ́ Ọlọrun (Iṣe Awọn Aposteli 1:9-11), nibiti Ó wà kọjá ibi ti Satani le è dé.

4. Lẹhin ìgbàti a ti gba Jesu sókè ọ̀run, kinni Satani ṣe si ijọ?
**Ifihan 12:13**
Nígbàtí dragoni naa ri pé a lé oun lọ si ilẹ̀ ayé, o ṣe _________ si obinrin ti o bí ọmọkunrin naa.
Àkíyèsí: Nígbàtí o di wípé satani ko le korira Jesu mọ́, o pinnu lati má a pa Jesu lara nipa bibinu si ijọ.

5. Nibo ni obinrin naa lọ ni àkókò ìbẹ̀rù inúnibíni yi? Bawo lo ṣe pẹ́ tó?
**Ifihan 12:6**
Obinrin naa si sá lọ si __________ , nibiti a gbé ti pèsè àye silẹ̀ dè é lati ọwọ́ Ọlọrun wá, pe ki nwọn ki o maa bọ́ ọ nibẹ̀ li ẹgbẹfa ọjọ o le ọgọta.
Àkíyèsí: Obinrin náà (ijọ Ọlọrun) salọ sí inú aginjù (ibi to jìnnà rere ninú ayé) lati sapamọ́ fún awọn ọtá rẹ̀. Ó jẹ́ ìtàn tí gbogbo ènìyàn mọ̀ pé ni ìgbà tí òkùnkùn si bo ojú awọn ènìyàn, àwọn ènìyàn Ọlọrun salọ sí inú ihò ilẹ ati pé wọn ndá nìkan gbé lori ilẹ̀ ayé, titi ti o fi dé agbègbè Amẹrika, lati wa ominira ẹ̀sìn ati ààbò kuro lọ́wọ́ inúnibíni papali. Ẹgbẹfa ọjọ́ o le ọgọta (1260) naa (ni a tún júwe rẹ ninu Bibeli bi oṣù mejilelogoji (42) tàbí ọdún mẹta ààbọ̀) wọn ntọka sí àkókò búburú ti ẹgbẹfa ọdun o le ọgọta (1260) ti inúnibíni laarin eyiti miliọnu kú nitori ìgbàgbọ́ wọn. Ní ààrín àkókò yi, ijọ Ọlọrun wa láàyè ṣùgbọ́n a kò mọ pàtàkì rẹ, agbẹkalẹ tí a lè fojú rí. (Wo afikún "Àwọn Ọdún Inúnibíni.")

6. Kinni awọn àmì meji miran lati mọ ijọ Ọlọrun tootọ?
**Ifihan 12:17**
Dragoni naa si binu gidigidi si obinrin naa, o si lọ ba awọn irú-ọmọ rẹ̀ iyoku jagun, ti nwọn npa ________ Ọlọrun mọ́, ti nwọn si di _______ Jesu Kristi mu.
Àkíyèsí: Ijọ Ọlọrun tó kù, ninu eyiti Ọlọrun npe awọn enyàn Rẹ̀ sí, wọn yio pa òfin Ọlọrun mẹwa mọ́ (pẹlu-pẹlu ọjọ́ Isinmi). Yio ni ẹ̀rí Jesu, ti iṣe ẹmí, tabi ẹ̀bùn ti isọtẹlẹ (Ifihan 19:10). Ọlọrun npe awọn ijọ ìgbà ikẹhin yi "èyí tí ó kù" nitori ti wọn jọra ninu ẹ̀kọ́ ati amuyẹ si awọn ijọ aposteli.

7. Bawo ni Jesu ṣe sọ wípé a o ṣe fi ìfẹ́ wa si Oun hàn?
**Johannu 14:15**
Bí ẹnyin ba fẹran mi, ẹ ó ________ òfin mi mọ́.
**1 Johannu 5:3**
Nitori èyí ni ifẹ Ọlọrun, pe ki awa ki o pa ________ rẹ̀ mọ́: òfin rẹ̀ kò si nira.
Àkíyèsí: Nínú ìtàn ti a sọ ní ìbẹ̀rẹ̀, Solomoni le e mọ ìyá ọmọ tootọ nipa ìfẹ́ àìṣẹtan to fi hàn. Ni ọ̀nà kanna, ijọ Ọlọrun tootọ ni a o mọ̀ nipa ìfẹ́ ifira-ẹni rúbọ ati ìpinnu lati pa òfin Jesu Rẹ̀ mọ́ látọkànwá.

8. Kinni ọ̀rọ̀ awọn angẹli mẹta tí ijọ Ọlọrun yio ma waasu ni ìgbà ikẹ̀hìn?
**A. Ifihan 14:7**
O nwi li ohùn rara pe, Ẹ bẹru Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun un; nitori ti wakati ________ rẹ̀ dé: ẹ si __________ fun ẹniti o dá ọrun, oun ayé, ati okun, ati awọn orisun omi.
**B. Ifihan 14:8**
Angẹli miran si tẹ̀le e, o nwipe, __________ _____ , Babiloni ti o tobi nì wó, eyiti o ti nmú gbogbo orilẹ-èdè mu ninu ọti-waini ibinu àgbèrè rẹ̀.
**D. Ifihan 14:9,10**
Angẹli kẹta si tẹle wọn, o nwi li ohùn rara pé, Bi ẹnikẹni ba nforibọ́ alẹ fun __________ nì, ati aworan rẹ̀, ti o si gbà _______ si iwajú rẹ̀ tabi ọwọ́ rẹ̀, Oun pẹlu yio mu ninu ọti-waini ibinu Ọlọrun, ti a tú jade li aini àbùlà sinu ago irunu rẹ; a o si fi iná ati sulfuru dá a lóró niwaju awọn angẹli mímọ́, ati niwaju Ọdọ-Agutan.
Àkíyèsí: Awọn ọ̀rọ̀ awọn angẹli mẹta wọnyi dúró fun ẹ̀kọ́ mẹta tí ijọ Ọlọrun yio waasu ní kánkán kí Jesu tó padà wá.

9. Awọn wo ni ijọ Ọlọrun yio waasu ọ̀rọ̀ wọ̀nyí fun?
**Ifihan 14:6**
Mo si ri angẹli miran nfò li agbedemeji ọrun, ti oun ti ihinrere aiọ́ nipẹkun lati waasu fun awọn ti ngbé ori ilẹ̀ ayé, ati fun gbogbo __________ , ati _________ , ati èdè, ati eniyàn.


YOR-SP17.indd 1
12/12/12 5:48 PM

Àkíyèsí: Ijọ Ọlọrun ti ìgbà ikẹhìn yio waasu kókó-mẹta ẹ̀kọ́ yi fun gbogbo orilẹ-èdè ayé.

10. Kinni gbèdéke tí Ọlọrun fún wa ninu ọ̀rọ̀ Rẹ̀ lati ràn wa lọ́wọ́ lati dá ijọ Rẹ̀ ni ìgbà-ikẹhìn mọ̀?
    A. Yio farahàn ati pé yio se iṣẹ ti o se e fojuri lẹhin ti o ba ti jade kuro ninu aginjù ní ọdun ẹ́íó̀ì (Ifihan 12:6, 13-17).
    B. Yio kọni ní otitọ kanna ti awọn aposteli ti kọ́ awọn eniyàn, gbogbo ẹ̀kọ́ rẹ yio si sowọ̀pọ̀ pẹlu Bibeli (Ifihan 12:7).
    D. Yio pa ôfin mẹwẹwa mọ́, titi de ọ̀rí pipa ọjọ isinmi Bibeli mọ́ (Ifihan 12:17).
    E. Yio ni ẹmi isọtẹlẹ (Ifihan 12:17; 19:10).
    Ẹ. Yio kede ẹ̀kọ́ Ọlọrun mẹta ti ìgbà ikẹhìn ti Ọlọrun ni ohùn rara (Ifihan 14:6-14).
    F. Yio jẹ́ rírìn kiri de gbogbo orilẹ-èdè (Ifihan 14:6).
    G. Yio kọ́ni ní ihinrere ainipẹkun ti iṣe ìgbàlà nipa Jesu Kristi nikan (Ifihan 14:6)

Àkíyèsí: Ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn Kristiani tó dára ni wọn jẹ́ ọmọ ijọ ti wọn ko kún ojú òṣùnwọ̀n meje wọ̀nyí. Bi o ti wu kí ó rí, irú ijọ bẹ́ẹ̀ ko le jẹ ijọ Ọlọrun to ṣẹkù nínú èyí ti Ọlọrun yio ma pe awọn ọmọ Rẹ̀ tootọ sí, nitori pé ijọ Rẹ̀ ni ìgbà-ikẹhìn gbọdọ kún ojú oṣuwọn mejeeje yi.

11. Jesu fun ọ ni kókó meje ti isọtẹlẹ idanimọ̀ yi , o si wi pé, "Lọ wa ijọ Mi." Kinni Jesu seleri nípa wíwá ijọ Rẹ̀?
    **Luku 11:9**
    Emi si wi fun nyin, Ẹ bere, a o fi fun nyin; ẹ wa kiri, ẹnyin o si _______ ; ẹ kànkùn, a o si ṣi i silẹ̀ fun nyin.

12. Melo ni ijọ tí yio kún ojú òṣùnwọ̀n meje yi ni gbogbo agbáyé?
    **Efesu 4:5**
    Oluwa kan, _________ ________ , baptismu kan.

Àkíyèsí: Ijọ kan soso ni gbogbo agbáyé ni o kún ojú gbogó bo òṣùnwọ̀n wọ̀nyí - Ijọ Onireti Bíbọ̀ Jesu lẹ́ẹkeji (Seventh-day Adventist Church), oun naa ni o mu ẹ̀kọ́ yi wá fun ọ. Ní bayi, o ti nwaasu ẹ̀kọ́ mẹta ti àwọn angẹli ninu Ifihan ẹ́è:ùọ́ẹ̀ẹ̀ kakiri àgọ́ báyé. Miliọnu si ndáhùn.

13. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ijọ lo n pe ara wọn ni Kristiani. Njẹ́ èyí sọ wọn di ijọ Ọlọrun tootọ bí?
    **Isaiah 4:1**
    Ati li ọjọ́ naa obinrin meje yio dìmọ́ ọkunrin kan, wipe, Awa o jẹ _________ ara wa, awa o si wọ_______ ara wa: kìkì pe, jẹ ki a fi __________ rẹ pè wa, lati mu ẹ̀gàn wa kúrò.

Àkíyèsí: Ounjẹ dúró fun Ọ̀rọ̀ Ọlọrun (Johannu ù:éú,úẹ́,úẹ̀,úé), ati aṣọ dúró fun ododo (Ifihan ẹ́ó:ì). Awọn obinrin meje ti inu asọtẹlẹ yi ní ounjẹ ti wọn (ìmọ̀ otitọ́) ati pé, wọn yio ma a wọ aṣọ ara wọn (ododo). Wọn kò fẹ́ aṣọ tí kò ní àbàwọ́n ti ódodo Kristi. Ohun ti wọn fẹ́ ni lati gbà orukọ Jesu, bóyá nitoripé Bibeli sọ wipé, "Kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fi fun ni ninu eniyàn, nipa eyiti a le fi gbà wa là." Iṣe Awọn Aposteli è:ẹ̀ẹ̀.

14. Lẹsẹkẹsẹ ti ẹnikan ba ti ri ijọ Ọlọrun otitọ́ ti ìgbà ikẹhìn, ṣe o ṣe pàtàkì lati di ọmọ ijọ bí?
    **Ixe Awọn Aposteli 2:47**
    Nwọn nyin Ọlọrun, nwọn si ni ojurere lọdọ eniyàn gbogbo. Oluwa si ________ kún _________ li ojoojumọ awọn ti a ngbàlà.



Àkíyèsí: Bẹ́ẹ̀ni, didi ọmọ ijọ Ọlọrun ti ìgbà ikẹhìn ṣe pàtàkì gidigidi. Wo bi Ọlọrun se dahun ibeere yi gbangba nípa didi ọmọ ijọ:

- A pè wá sinu ara kan (Kolosse 3:15)
- Ara naa ni ìjọ (Kolosse 1:18)
- A wọ inú ara naa nipasẹ baptismu (ẹ́ Korinti 12:13)

O ṣe pàtàkì gidigidi lati wọ inu ìjọ Ọlọrun loni gẹ́gẹ́ bi o ti ṣe pàtàkì lati wọ inú ọkọ̀ ní ọjọ́ Noa. Oluwa wípé; "Ìwọ wá, ati gbogbo awọn ara ilé rẹ sinu ọkọ̀." Genesisi 7:1.

15. Ọ̀nà abayọ melo ló wà ni ìgbà ayé Noa?
    **Heberu 11:7**
    Nípa ìgbàgbọ́ ni Noa, nigbati Ọlọrun kilọ ohun ti a kò ì ti iri fun un, o bẹ̀rù Ọlọrun, o si kàn _________ fun ìgbàlà ilé rẹ̀, nípa èyi ti o dá ayé lẹbi, o si di ajogún ododo ti iṣe nipa ìgbàgbọ́.

Àkíyèsí: Jesu sọ wípé, àkókò ti yio saajú wíwá Oun lẹ́ẹkeji yio dabi ọjọ́ Noa (Luku 17:26). Ọ̀nà abayọ kan péré ni yio sì wà gẹ́gẹ́ bi o ti jẹ́ pé ọkọ̀ kan lo wà ni ọjọ́ Noa.

16. Níwọ̀n ìgbà ti o jẹ́ wípé ọ̀pọ̀ awọn olotitọ Kristiani si wà ni ijọ miran ati pé ijọ otitọ kan ni o ṣẹ́kùn to jẹ́ ti Ọlọrun, kínnin yio ṣẹlẹ̀ si awọn olotitọ́ Kristiani wọnyi?
    **Johannu 10:16**
    Emi si ní awọn agutan miran, ti kì iṣe ti agbo yi: awọn li emi kò le ṣe alaimu __________ pẹlu, nwọn o si __________ ohùn mi; nwọn o si jẹ agbo _________ , oluṣọ-agutan kan.
    **Ifihan 18:2,4**
    O si kígbe li ohùn rara, wípé Babiloni nlá ṣubú, o subú, o si di ibuọ́ joko awọn ẹmi èṣu, ati ihò ẹmi aimọ́ gbogbo, ati ile ẹyẹ àimọ́ gbogọ́ bo, ati ti ẹyẹ ìrira, Mo si gbọ́ ohùn miran lati ọ̀run wá, nwipe, Ẹ ti inu rẹ̀ __________ , ẹnyin __________ mi, ki ẹ má baa ṣe alabapin ninu ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, ki ẹ má baa si ṣe gbà ninu iyọnu rẹ̀.

Àkíyèsí: Jesu yio pe gbogbo awọn olotitọ ati olododo ti wọn ntẹle E lati jade kúrò ní Babiloni. Wọn yio gbọ́ ohùn Rẹ̀, wọn yio dáhùn, wọn yio si wọ inú Ijọ òtitọ́ ìgbà-ikẹhìn Rẹ̀.

## Èsì Rẹ

Jesu npè ọ́ loni lati wọ inú ìjọ Rẹ̀ ti ìgbà ìkẹhìn yi ninu àābò to dájú. O ṣe iyebíye fun Un. Ṣe o fẹ́ dahùn ìpè Rẹ̀ bayi?

ÌDÁHÙN: ______________________



# Àfikún

Ipele yìí pèsè awọn irohìn afikún fun kikẹkọ tẹsíwajú.

### Àwọn Ọdun Inúnibínu

Ẹgbẹfa ọdún o le ọgọta (1260) inúnibíni ni Bibeli ntún sọ, nitori ninu ìtàn èyí jẹ́ ohun to burú jù lati kojú awọn eniyàn Ọlọrun (Matteu 24:21). A npè é ni Ẹgbẹfa ọjọ́ o le ọgọta (1260), oṣù mejilelogoji (42) àti mẹta àti àābọ̀ àkókò, tabi ọdún (Ifihan 12:6,14; 13:5; Danieli 7:25). Bi a ba lo kalẹnda awọn Ju ti o ni ẹgbaa le ogọta (360) ọjọ́ ninu ọdun kan, gbogbo àkókò yi ni a rò pọ̀ ti o jẹ́ Ẹgbẹfa ọdún o le ọgọta (1260). Ọjọ́ kan jẹ́ ọdún kan (Esekieli 4:6, Numeri 14:34).

Ìtàn fi ye wa pé agbára papasi ni agbara to nṣe inùnibíni fun Ẹgbẹfa ọdún o le ọgọta (1260) náà. Àkókò naa bẹ̀rẹ̀ ni ọdun A.D. 538, nígbàtí papali jẹ́ agọ́ bara nlá ni aarin Kristiani ni agbáyé nipaṣẹ aṣẹ ijọba Roman Justinian. Ninu rẹ, ni o ti rí bisọpu Romu gẹ́gẹ́ bí i olórí gbogbo ìjọ. Lẹta yi di ara nọmba tí a fi pamọ́ fún Justinian nìkan, èyití iṣe ìbẹ̀rẹ̀ ôfin ti ijọba. Àkókò náà parí ní ọdún 1798 nigbati ọgágun Napoleon, Aleṣander Berthier, kó popu ní ẹrú. O kéré tán aadọta miliọnu awọn Kristiani ló padanu ẹ̀mí wọn ni àkókò inunibini yi.

### Kókó Mẹta to ṣe Pàtàkì

Awọn kókó mẹta to ṣe pàtàkì julọ si awọn eniyàn Ọlọrun ni a fi ìdí rẹ kalẹ̀ ninu iwé Ifihan 12:10-12.

Awọn kókó náà niwọnyí:

1. Jesu ṣẹgun Satani, olùfisù awọn arakunrin lori agbelebu.
2. Gbogbo wa pẹlu le ṣẹgun rẹ (satani) nipa ẹ̀jẹ̀ Jesu ati nipa síwsọ̀rọ̀ nípa ẹ̀rí wa.
3. Inu nbí eṣù nitori o mọ̀ pé àkókò oun kéré. A ko le e retí pé ki o ma ṣe jẹ̀jẹ̀. Oun ni ọ̀tá wa to burú julọ.

Ẹ̀kọ́ naa ni pé Jesu, ẹniti O ti ṣẹgun Satani, O fi agbara Rẹ̀ tíkò lákàwé fún wa bí i ẹ̀bùn ọ̀fẹ́. Pẹlu agbara Jesu ninu ayé wa, a kò le e ri ìjákulẹ̀. Ibinu Satani kò le e pa wa lára. Ọ̀tá ti a ti ṣẹgun ni. A ṣẹgun rẹ ninu ogun ọrun, a si le e jade. A ṣẹgun rẹ nipaṣẹ Jesu lori agbelebu, o si sọ ijọba rẹ nù. A o sì ṣẹgun rẹ̀ ní ọ̀nà tó bá ôfin mu nínú idajọ́, a o sì tún ṣẹgun rẹ̀ nígbàtíí o ba gbógun ti ilú mímọ́ Ọlọrun. Ni àkótán, yio jẹyà wipe a a bà a jẹ́ ninu ayé nínú adagun iná. Ati pé, iyanu to ga jù, Jesu seleri pé, a o ṣẹgun rẹ ninu ìjà rẹ lati pa iwọ ati emi run. Irú ọ̀rọ̀ ìrètí nlá wo niyi lati ọ̀dọ̀ Jesu!

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP17.indd 2 12/12/12 5:48 PM